# Dajudaju arakunrin kan bi Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere pe: Isilaamu wo lo fi n loore julọ? O sọ pe: «Ki o maa funni ni ounjẹ, ki o si tun maa salamọ si ẹni ti o mọ ati ẹni ti o ko mọ

Lati ọdọ Abdullāh ọmọ ‘Amru - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji -: Dajudaju arakunrin kan bi Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere pe: Isilaamu wo lo fi n loore julọ? O sọ pe: «Ki o maa funni ni ounjẹ, ki o si tun maa salamọ si ẹni ti o mọ ati ẹni ti o ko mọ».
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Wọn bi Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - leere pe: Awọn iwa Isilaamu wo lo fi n lọla julọ? Ni o wa darukọ awọn iwa meji: Alakọkọọ: Pipọ ni imaa fun awọn alaini ni ounjẹ, ti saara ati ẹbun ati igbalejo ati ikolẹnujọ sì tun wọ inu rẹ, ati pe ọla ifunni l'ounjẹ tun kanpa ni awọn asiko ebi ati ọwọn gogo. Ẹlẹẹkeji ni: Sisalamọ si gbogbo musulumi, o mọ ọn ni tabi o ko tiẹ mọ ọn.



النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee